# AIMOORE AWỌN ỌMỌ ISRAẸLI ÈTÒ IRAPADA
## 1 Peteru 1:1-12
## ẸKỌ 104 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun" (Johannu 3:16).**

### Pipé Eniyan Ni Ibẹrẹ

Ọlọrun dá eniyan ki o le maa sin In, ki o si le maa yin In logo, O gbin Ọgbà daradara kan fun eniyan lati maa gbé, O si fun un ni ohun gbogbo ti o le fẹ lati mu inu rẹ dùn. Ọlọrun tikara Rẹ a maa sọkalẹ ni itura ọjọ lati ba awọn eniyan ti O dá rìn. Ṣugbọn ẹlomiran wá sọdọ wọn pẹlu. Satani wọ Ọgbà alaafia naa o si mu ki awọn ọmọ Ọlọrun dẹṣẹ.

Satani ti wà ni Ọrun nigba kan ri gẹgẹ bi olori angẹli, ṣugbọn o wa di agberaga pupọ, o si fẹ lati ba Ọlọrun dọgba; nitori bẹẹ oun ati awọn ọmọ-ẹyin rẹ, idamẹta awọn angẹli ti n bẹ ni Ọrun, ni a lé kuro, ti a si ṣe idajọ iya ayeraye fún. Kò fẹ ki eniyan bọla fun Ọlọrun ki o si gbọ ti Rẹ, ṣugbọn o n wa ero ti yoo maa tọ ọ lẹyin nitori eyi ni o ṣe n wá oju rere Adamu ati Efa, ti o si n fẹ mu wọn yipada kuro lọdọ Ọlọrun.

Ni irisi ejò, Satani wọ Ọgbà naa o si sọ fun Efa pe wọn ki yoo ku iku kiku kan rárá, bi Ọlọrun ti wi, bi wọn ba jẹ lara igi imọ rere ati buburu. Dipo eyi, wọn yoo gbọ́n bi Ọlọrun. A ti kọ ẹkọ pe ṣiṣe aigba Ọrọ Ọlọrun gbọ ni gbòngbò gbogbo ẹṣẹ, a si ri i nihin pe aigbagbọ Efa ninu ohun ti Ọlọrun ti sọ ni o fa aigbọran rẹ akọkọ, Adamu fi eti si imọran ọta pẹlu, awọn mejeeji si jẹ ninu eso aigbọdọjẹ naa. Eyi si ni ipari alaafia wọn. Nitori aigbọran wọn a le wọn jade sinu ayé àdágbé lati maa ṣe laalaa funra wọn, ibarẹ wọn pẹlu Ọlọrun si já.

Ẹṣẹ Adamu ati Efa ni a n pè ni "iṣubu." Eniyan ṣubu ninu ẹṣẹ, o si sọ aworan Ọlọrun ati oju rere Rẹ nù. Nitori Adamu ati Efa dẹṣẹ, olukuluku eniyan ti a bi sinu aye ni a bi pẹlu ẹ̀dá ẹ̀ṣẹ ninu rẹ, eyi ti o n mu ki o ṣe ohun ti kò tọ́ nigba ti o dagba to lati mọ iyatọ laaarin rere ati buburu. Nigba ti o si ti dẹṣẹ lọna bẹẹ, o yẹ si iku, nitori ofin Ọlọrun sọ pe, "Ọkàn ti o bá ṣẹ̀, on o kú" (Esekiẹli 18:4).

### Aanu Ọlọrun

Ṣugbọn Ọlọrun fẹran Adamu ati Efa sibẹ; o dun Un pupọ pe wọn ko fẹran Rẹ gẹgẹ bi O ti n fẹ, sibẹ O ṣe tan lati dariji wọn bi wọn o ba ronupiwada. Ọlọrun ni eto kan nipa eyi ti eniyan le tun fi ni aworan ati oju rere Ọlọrun. Kò si ọkunrin, obinrin tabi ọmọde ti o yẹ ki o tun jẹ iyà ainipẹkun, nitori Jesu ti wá lati ṣe irapada araye ki O si sọ ọ di mimọ́ gẹgẹ bi eniyan ti wà ri ṣaaju iṣubu..

Gẹrẹ ti Ọlọrun ti le Adamu ati Efa jade ninu Ọgbà, O ṣe ileri lati rán Oludande ti yoo ṣẹgun ọta, ti yoo si fun eniyan ni agbara lati "mã lọ, lati igbayi lọ má dẹṣẹ̀ mọ́." Asọtẹlẹ kin-in-ni nipa Jesu wà ninu Gẹnẹsisi 3:15, nibi ti Ọlọrun ti ṣe ileri pe a o bi Ọmọ kan, ẹni ti yoo dagba ti yoo si jẹ́ Olugbala araye. Oun ki yoo jẹ ọmọ kan bẹẹ ṣá, ṣugbọn Ọmọ Ọlọrun tikara Rẹ, Ẹni ti yoo wá lati ba awọn eniyan gbe ati lati kú dipo wọn, pe nipa Ẹjẹ Rẹ ti a o ta silẹ ki wọn le ni igbala (irapada).

Ofin Ọlọrun "Ọkàn ti o bá ṣẹ̀, on o kú" duro sibẹ; ṣugbọn Jesu fẹ lati kú dipo wa. Jesu, Ọmọ Ọlọrun ti a mọ̀ si Iṣura didan ju lọ ni Ọrun, Ayanfẹ Ọlọrun yọọda lati fi Ibugbe Rẹ daradara silẹ lati wá si ayé yii lati jiya ati lati kú ki a ba le tẹ́ Ofin Ọlọrun lọrun, ki eniyan má ba ni lati jiya fun ẹṣẹ ara rẹ. Nitori ti Jesu ku (fun ẹṣẹ wa), a le ni iye ainipẹkun bi a ba tọ Ọ lọ pẹlu ironupiwada, ti a si bẹ Ẹ pe ki O jẹ ki Ẹjẹ Rẹ wẹ ọkan wa.

### Itumọ Ti Ọlọrun Fun Ikú

Boya iwọ ro pe Adamu ati Efa kò ku -- gẹgẹ bi Ọlọrun ti sọ pe wọn o kú bi wọn ba ṣe aigbọran – nitori wọn ṣi wa laaye lẹyin Ọgbà. Ki ni Ọlọrun pè ni ikú? Lẹyin ti Lasaru ti "kú" gẹgẹ bi èdè ti wa - fun ọjọ mẹrin, Jesu wi pe "Lasaru ọrẹ́ wa sùn" (Johannu 11:11). Ninu Daniẹli 12:2 a ka a pe "Ati ọ̀pọlọpọ ninu awọn ti o sùn ninu erupẹ ilẹ ni yio ji, awọn miran si ìye ainipẹkun, ati awọn miran si itiju ati ẹ̀gan ainipẹkun." A n pe awọn eniyan bẹẹ ni oku, ṣugbọn Ọlọrun sọ pé wọn sùn ni.

Njẹ ki ha ni iku ẹlẹṣẹ? Eyi ni ipò iyà ainipẹkun, ninu eyi ti ẹlẹṣẹ yoo ṣegbe sí titi laelae, bi ko ba ronupiwada. Jesu sọ fun wọn nibi ase ni pe, "Wakati mbọ̀, o si de tan nisisiyi, nigbati awọn okú yio gbọ́ ohùn Ọmọ Ọlọrun: awọn ti o ba gbọ yio yè: (Johannu 5:25). O n sọ nipa awọn eniyan ti wọn wà laaye sibẹ, ṣugbọn wọn jẹ ẹlẹṣẹ. O si pe wọn ni oku. Paulu sọ fun Timoteu pe, "Ṣugbọn ẹniti o ba fi ara rẹ fun aiye jijẹ, o kú nigbati o wà lãye" (1 Timoteu 5:6).

### Awọn Asọtẹlẹ Nipa Jesu

A kọ́ ninu awọn ẹkọ wa lori ijọsin inu Agọ ninu aginju pe awọn eniyan tilẹ le ri igbala ọpọlọpọ ọgọrun ọdun ṣaaju ki Jesu to dé inu aye, bi wọn ba foju sọna fun bibọ Rẹ pẹlu igbagbọ. Gbogbo ọdọ-agutan ati orişirişi ẹran miiran ti

wọn n ta ẹjẹ wọn silẹ nigba ni jẹ apẹẹrẹ Jesu. Kiki awọn Ọmọ Israẹli nikan ni wọn kọ́ nipa ifẹ Ọlọrun nipasẹ awọn wolii, nitori wọn jẹ ayafẹ eniyan Ọlọrun. Ọlọrun pe Abrahamu lati fi ilu ibilẹ rẹ silẹ ki o si di ẹni iyasọtọ, iranṣẹ Ọga-ogo; nipasẹ awọn iru-ọmọ rẹ̀, awọn ẹni ti o di orilẹ-ede Ju lẹyin ọdun pupọ, ni Ọlọrun ti fun araye ni imọ nipa eto igbala.

Abrahamu mọ pe Jesu n bọ wà sinu aye, nitori Jesu sọ fun awọn akọwe ati Farisi pe: "Abrahamu baba nyin yọ̀ lati ri ọjọ mi; o si ri i, o si yọ̀" (Johannu 8:56). Jobu pẹlu, ẹni ti oun naa wà ninu aye ni nnkan bi akoko kan naa pẹlu Abrahamu, gbagbọ pe Jesu yoo wá si aye. O kọ ọ silẹ ninu iwe pe, "Ati emi, emi mọ̀ pe Oludande mi mbẹ li ãyè ati pe on bi Ẹni-ikẹhin ni yio dide soke lori erupẹ ilẹ" (Jobu 19:25). Gbogbo awọn wolii ni wọn sọ nipa Jesu, gẹgẹ bi Ọlọrun ti mí si wọn lati sọ. Eredi iwaasu wọn ni lati dari awọn eniyan si ọdọ Jesu, Olugbala gbogbo eniyan ti yoo ba gba A gbọ.

**Òye Awọn Angẹli Nipa Jesu**

Awọn Angẹli Ọrun paapaa mọ pe Jesu n bọ̀ wá sinu aye. Wọn n nọga lati wo ohun ijinlẹ naa, pe Ọmọ Ọlọrun le wá ku fun awọn eniyan ẹlẹṣẹ, ki O si ṣe wọn yẹ fun Ọrun. Angẹli ni o ṣe ikede fun Josẹfu pe a o tipasẹ Maria bi Jesu. Angẹli naa sọ pe, "On ni yio gbà awọn enia rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn." Ni oru ọjọ naa ti a si bi Kristi, ogunlọgọ awọn angẹli ni wọn kọrin ayọ ibi Rẹ̀ ni ibujẹ-ẹran ti Jesu sùn si ni Bẹtlẹhẹmu. Wọn mọ pe Jesu wá si aye bi Ọdọ-agutan Ọlọrun ti a o fi ṣe etutu fun ẹṣẹ, wọn si yin In logo nitori iyà ti O yọọda ara Rẹ̀ lati jẹ.

**Awọn Iranṣẹ Satani**

Nigba ti eniyan di ẹlẹṣẹ, wọn ko si labẹ itọni Ọlọrun mọ, ṣugbọn wọn ti sọ ara wọn di iranṣẹ ẹni ibi ni. Satani fi ero ati ifẹ buburu ti rẹ̀ si wọn lọkan; a si n ri apẹẹrẹ ibinu, owu, ikorira ati orikunkun ninu awọn ọmọ kékèké paapaa. Bi wọn si ti n dagba ni awọn iwa wọnyii n dagba pẹlu wọn – ti awọn kan le pọ ju ti awọn miiran lọ -- nigba miiran a si maa kó awọn eniyan sinu wahala nla, bi olè jija ati ipaniyan.

Ṣugbọn bi eniyan ba tilẹ ni iwa ọmọluwabi, ti o si le kapa awọn iwa ibi wọnni, sibẹ wọn wà ninu iṣẹda rẹ̀ titi ẹni naa yoo fi tọ Jesu wa fun oore-ọfẹ igbala. Ko si eniyan ti yoo le wọ Ọrun bi Ẹjẹ Jesu kò ba yí iṣẹda rẹ̀ pada ki o si mu awọn iwa abinibi buburu wọnni kuro. Ko si eniyan ti o le funra rẹ̀ mu irugbin (ẹda) ẹ̀ṣẹ kuro ninu ọkàn rẹ̀.

**Ọkàn Titun**

Ko si ẹni ti o le ṣe alaye ohun ti n ṣẹlẹ nigba ti ẹlẹṣẹ kan ba di atunbi. Ko si ẹni ti o le ri ọkàn naa ti a yipada. Nigba ti Nikodemu, ijoye ti o tọ Jesu wa ni oru, beere fun alaye fun iyipada nlá nlà ti n ṣẹlẹ nigba ti eniyan ba di Onigbagbọ (atunbi), Oluwa lo apejuwe iṣẹ ti afẹfẹ n ṣe. Eniyan le ri awọn igi ti n mì siwa mì sẹyin ninu afẹfẹ naa; o le ri ọkọ oju-omi ti afẹfẹ n gbe lọ, ṣugbọn ẹni kan ha ti i ri afẹfẹ nigba kan ri? Nigba ti a ba ri nnkan ti n ho bi ọṣẹ lori omi, a mọ pe iji lile n jà, ṣugbọn a ko le ri i. Bakan naa ni awọn eso oore-ọfẹ igbala maa n fara han gbangba. Bi a ko tilẹ le ri ọkan ti a ti yipada a le ri ayọ̀ ninu igbesi-ayé awọn eniyan ti kò ti ni ayọ̀ nigba kan ri. A mọ pe bi o tilẹ jẹ pe wọn ti maa n purọ nigba kan ri, wọn ko ni purọ mọ́. Wọn ko ni jale mọ́, tabi binu, bẹẹ ni wọn ko ni korira ẹnikẹni mọ́.

**Ẹda Titun**

Nigba ti eniyan ba tọ Jesu wa ti o si bẹ Ẹ pe ki O dari ẹṣẹ ji oun: lẹyin idariji, yoo di "ẹda titun" ninu Kristi Jesu, yoo si fẹran Oluwa ju ohunkohun ati ẹnikẹni lọ ninu ayé. Onigbagbọ n fẹ lati ṣe ohun ti o wu Oluwa ju ohun gbogbo lọ. Yatọ si pe eniyan n fẹ lati ṣe, a maa n fun un ni agbara nipa Ẹjẹ Jesu lati gbe igbesi-aye rẹ̀ gẹgẹ bi Bibeli ti sọ fun ni.

Awọn eniyan kan wà ti n sọrọ pupọ nipa sisọ awọn ọdaran di ẹni rere. Wọn n ṣe alaye pe ko yẹ ki a maa jẹ awọn ọdanran niya, ṣugbọn o yẹ ki a fihan wọn pe ọna si igbesi-aye ti o dara ju bẹẹ lọ wà. Ṣugbọn eniyan diẹ ni o n ṣe rere lẹyin iru itọni bayii. Wọn le fẹ fi ole jija ati iwa buburu wọn iyoku silẹ, ṣugbọn wọn ko le ṣe e ninu agbára ti wọn. Ṣugbọn nigba ti Jesu ba wọ inu ọkàn wọn nipa oore-ọfẹ igbala, wọn ko tun ni dẹṣẹ mọ́. Gbogbo ẹṣẹ wọn atijọ ni Oluwa maa n dariji ti O si n wẹ̀ nù, wọn ki i si dá ẹ̀ṣẹ titun mọ́.

Awọn kàn ro pe awọn ọlọṣa ati apaniyan ni o yẹ lati ni igbala ṣugbọn pe bi awọn funra wọn ko ba ti ṣe nnkan ti o buru ju ri, kò jẹ dandan fun wọn lati wá aanu. Ṣugbọn Paulu kọwe pe; "Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọkrun" (Romu 3:23). Ko si ẹni ti yoo le ti ipa ododo ara rẹ̀ wọ Ọrun, bẹẹ ni eniyan ko le fi iṣẹ rere ṣiṣe wọle. A ni lati wá sọdọ Jesu, ki a bẹ Ẹ pe ki O fi Ẹjẹ Rẹ wẹ wa ki a ba le ri igbala. Lẹyin ti a ba si ri igbala a o pa ifẹ Ọlọrun mọ́ ninu ọkàn wa nipa ifararubọ ati adura ojoojumọ. "Ẹnikẹni ti o ba ngbé inu rẹ̀ ki idẹṣẹ" (1 Johannu 3:6). Ko si ẹni ti n dẹṣẹ ti yoo de Ọrun.

**Irapada**

Irapada ni lati ra nnkan ti o sọnu pada. Nigba ti a ṣubu sinu ẹṣẹ Jesu ra wa pada; eyi ni a n pe ni irapada. Irapada wa ju riri idariji ẹ̀ṣẹ wa gbà. Jesu kú dipo wa, lati wẹ ẹ̀ṣẹ wa nù, ṣugbọn O tun ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun isọdimimọ́ wa pẹlu (Heberu 13:12). Nigba ti Jesu kú, O pese fun iwosan ara wa pẹlu: "Ẹniti on tikararẹ̀ fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa lori igi, pe ki awa ki o le di okú si ẹ̀ṣẹ ki a si di ãye si ododo: nipa ìnà ẹniti a mu nyin larada" (1 Peteru 2:24).

Nnkan ti o wà ninu eto irapada tilẹ ju igbala ọkàn ati iwosan ti ara wa nikan. Nigba ti Jesu ba tun pada wa Oun yoo dá ara wa nide pẹlu (Romu 8:23). Ki eniyan to dẹṣẹ ninu Ọgbà, kò ṣaisan; ṣugbọn nigba ti o ṣubu o fa aisan wa sori gbogbo eniyan. Nisisiyii, Jesu n wo wa san nipa Ẹjẹ Rẹ̀ nigba ti ara wa kò ba da, ṣugbọn akoko naa n bọ -- titi fi di akoko ipalarada awọn eniyan mimọ -- ti olukuluku eniyan ni lati kú ikú ti ara. Awọn Onigbagbọ Aṣẹgun ti o ti wọ inu iboji lọ ṣaaju wa yoo tun jinde pẹlu ara ologo nigba ti Jesu ba de, "Nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa ó si ma wà titi lai lọdọ Oluwa" (1 Tẹssalonika 4:17).

**AWỌN IBEERE**

1. Ni aworan wo ni Ọlọrun dá eniyan?
2. Bawo ni o ti pẹ to ti eniyan fi wà ninu aworan yii?
3. Ede wo ni a n lò lati fi sọ nipa ẹṣẹ ti eniyan kọkọ dá?
4. Awọn wo ni o di ẹlẹṣẹ nipa ẹ̀ṣẹ Adamu ati Efa?
5. Bawo ni eniyan ti n dagba to ki a tó ri awọn apẹẹrẹ ẹ̀ṣẹ ninu iwa rẹ̀?
6. Nigba wo ni Ọlọrun kọ́ ṣe ileri ọna lati bọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ?
7. Ki ni ofin Ọlọrun nipa ẹlẹṣẹ?
8. Bawo ni a ṣe le mu ofin yii ṣẹ lai jẹ pe awa funra wa jiya fun ẹṣẹ wa?
9. Ki ni Jesu ṣe fun ẹlẹṣẹ?
10. Ki ni awọn ohun ti o wà ninu igbala?